# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,582 FRIDAY DECEMBER 10, 1965 (2D)


## Awon Oşişe Iwe Irohin Post Fe Da Işe Sile

APAPA:— Ni deede agogo mejila oru ọjọ Işegun ti işe ọjọ kejo oşu yi ni awọn oşişe iwe irohin ti apapọ Ijọba eyiti a npe ni "Morning Post ati Sunday Post" awọn oşişe ti nwọn to ẹdẹgbẹta (500) fẹ binu da işẹ silẹ lori ẹkunwo ow o-oşu eyiti awọn oşişẹ na nbere lọwọ awọn Alakoso ile işẹ na lati le san fun wọn.

Ninu ọsẹ to kọja lọ yi ni awọn ẹgbẹ oşişẹ iwe irohin na kọ iwe fun awọn Alakoso ile işẹ iwe irohin na eyiti awọn oşişẹ na fi fun awọn Alakoso ile işẹ na ni ọjọ mẹrinla lati jiroro lori ẹkunwo owo-oşu eyi ti awọn ẹgbẹ oşişẹ na şe alaye pe ti awọn Alakoso na ko ba tete şe eto lori ohunti awọn nbere na pe awọn yio binu da işẹ silẹ.

Ni agogo mejila oru ọjọ Işegun ti işe ọjọ keje oşu yi ni ọjọ ti awọn oşişẹ na fun awọn Alakoso na ati pe o şe işẹ ki awọn oşişẹ na binu da işẹ silẹ laipẹ yi.

Ninu ọrọ Agbẹnusọ fun awọn ẹgbẹ oşişẹ na fun oniwe irohin wa nigbati o fi ọrọ njomitoro lẹnu rẹ ni o ti şe alaye pe gbogbo owo awọn oşişẹ ti o wa ni ile işẹ eto irohin ati awọn to nşiro owo ninu ile işẹ na ni awọn Alakoso na ti fun ni ẹkunwo owo-oşu ati pe awọn Alakoso ile işẹ na kuna lati fun awọn oşişẹ yoku Awọn oşişẹ na tun şe alaye pe ti awọn Alakoso na ko ba tete şe eto lori ẹkunwo owo-oşu na pe awọn yio da işẹ silẹ.

# ILE IGBIMỌ ASOFIN IJỌBA IWỌ ORUN ŞE IPADE

IBADAN.— Ni deede agogo mẹwa kutukutu owurọ ana ọjọ ọjọ'Bọ ti işe ọjọ kẹsan oşu yi ni awọn ọmọ Ile Igbimọ Aşofin Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria şe ipade ninu Ile Igbimọ Aşofin Ijọba Ipinlẹ na.

Onirohin wa ti o lọ si Ibadan fi ye wa wipe, ni deede agogo mẹsan abọ ni awọn enia ti bẹrẹsi de fun ipade ti nwọn fẹ şe na nigbati yio si fi di nkan bi agogo mẹwa, awọn enia na ti de.

Şugbọn bi awọn enia ti nwọn wa si ipade na ti şe pọ to, Alhaji D. S. Adegbenro, Adele Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aşiwaju ẹgbẹ Ajumọşepọ (UPGA pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ko lọ si ibi i p a d e ti nwọn şe ni ana.

Oniwe irohin wa, ti o lọ si ibi ipade na fi ye wa pe, nigbati on ko ri Alhaji Adegbenro ati awọn ọmọ ẹgbẹ rẹ ni on ba wa a lọ si ile rẹ, şugbọn akọwe rẹ sọ wipe ko si ni'le.

Nigbati awọn enia na bẹrẹ ipade gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ gba lati ọdọ oniwe irohin wa ni ọsan ana lati Ibadan nigbati ipa de na bẹrẹ, ọkan ninu awọn enia na da imọran wipe, ohunti o kọkọ yẹ ki awọn şe ninu ipade yi ni lati yan alaga titun fun Ile Igbimọ Iwọ Orun.

Gbogbo awọn enia na ni nwọn gba wipe o yẹ ki awọn le ni alaga ninu ijoko awọn na, ni ẹnikan ba tun da imọran wi pe on da imọran wipe, Alhaji Busari Obisẹsan ni on da ni imọran pe ki o jẹ alaga Ile Igbimọ na.

Gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na ni nwọn si fi ohun kan gba imọran na ko si ẹniti o lodi si i ni nwọn ba yan Alhaji Busari Obisẹsan ni Alaga Ile Igbimọ na.

Şugbọn ohunti o ya gbogbo enia lẹnu ni wipe nigbati nwọn yan Alaga tan, ti nwọn si nreti wipe ki alaga dide duro ni aye rẹ ki gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na le mọ ki o si tun bere işẹ rẹ titun ti nwọn şẹşẹ yan an fun ni nwọn ko ba ri ẹniti nwọn yan ni alaga.

Şugbọn lẹhin idakẹ jẹ ẹ diẹ ni Ọgbẹni Akinọla, ẹniti işe Akọwe Ile Igbimọ na ba dide duro ti o si şe alaye fun Ile Igbimọ na wipe on ti ri iwe gba wipe alaga na le wa si Ile Igbimọ na ni Oni yi.

## AWON OBA

Bakanna ni Oniwe Irohin wa tun lọ si Ile Igbimọ Aşofin awọn Ọba n i b i t i awọn na tun gbe nşe ipade ti wọn ni ana kanna.

Nigbati ipade awọn Ọba na bẹrẹ ni deede agogo mẹwa Owurọ ana, ọkan ninu awọn Alaiye ninu Ile Igbimọ na ni o kọkọ dide ti o si da imọran wipe o yẹ ki awọn le ni Olori ninu Ile Igbimọ na eyiti awọn nşe ipade rẹ ni Oni yi.

WO OJU EWE KẸFA

## AZIKIWE YIO DE LAIPE

EKO:— Ninu irohin kan ti a ri gbọ labẹlẹ fi ye wa pe olori ilẹ Naijiria, Dọkita Nnamdi Azikiwe to lọ si Lọndọnu lati lọ şe itọju ara rẹ ni a gbọ pe yio de laipẹ yi ati pe ọlọla Azikiwe ti gbadun bayi.

WO OJU EWE KẸFA



**Dokita Nnamdi Azikiwe**
OLORI APAPỌ IJỌBA ILẸ NAIJIRIA

# ỌRUNRERE O SHOYINKA

Ha ! ẹja nla
Lọ ninu omi
Erin wo
L'Oke amilaala
Fọlọrunṣọ ṣe bẹ
O d'ẹni ọrun
Alẹkeji Aremabọ

x x x x x x x

Ojọ nla
L'ọjọ kẹrindilogun
Oṣu kejila odun 1964
Abati Shoyinka
Jẹpe Ẹlẹda rẹ
A gbọ ju Igbanu
Ni irohin na
Jẹ f'awọn ẹbi
At'ọrẹ rẹ
Pe Iyẹru Ọkin lo

x x x x x x

Ha ! ba ṣe pe
Iku gb'owo ni
A ba fun un
Iba ṣepe Iku
Gba aṣọ ni
Aba fun un
Bi iku tilẹ
Bere agbo funfun

A ba ti kọ lati fun
Ṣugbọn iku ko gb,owo
Bẹni ki o gbobi
A f,ẹni rere

LATI ỌWỌ

## J. O. Shoyinka

Onitan Ajiran ilu Oku

To mulọ.
Ṣ,ajule ọrun lagandanragbọn
Ẹ s' oju aiye
Tabi ẹ ko ri ara
Nibiti igi gbigbe
Ti duro ṣanṣanṣan
Ibẹ ni igi tutu
Nwo lulẹ gbirigidi

X x x x x x x x
Hal ẹ ma
Fi iku yọ ẹda
Gbogbo wa ni ojọ nla
Tori gbese ni Iku
Gbogbo wa
La o san dandan
Ka pẹ laiye tit

Bi metusela
Lai ni adiẹ irana
Ko sisẹ
Ka ku lọmọde
Pẹlu adiẹ irana
Loṣa dara

Shoyinka ko ku
Isun Lo sun
Toripe bi ina ba ku
Eru ni fi i Boju

B'ọgẹdẹ ba ku
Ọmọ rẹ ni i
Fi r'ọpo
'Biọla ni baba
Fi rọpo ara rẹ

X X X X X

Oṣewẹ lede Yoruba
Bi Shoyinka ko si
On lo ṣe
Iwe Akọka lede Yoruba
Iwe Yoyọ l'ẹnu aiye
Iwe Itan Ijinle lede Yoruba
Gbedegbẹyọ Hausa
Ati bẹbẹ lọ
On na ni o si da
Ile iṣẹ itẹwe ti o pe ni
Iyeru Press & Bookshop silẹ
Nigba aiye rẹ

X X X X X X X X X X

Dabobo Fọrunṣọ Shoyinka
yẹru Ọkin
Ọmọ Ọlọffa
lalọmi Ọtaẹ abisu jorukọ
Ija adi loro Ọffa
Ija kan, ija kan
ti nwọn nja l'Ọffa
Ni ile Ọlalọmọ?
Oju talo ṣe
O ṣoju ebe
L'Ọffu
O ṣoju aporo
Ninu oko
Iba ṣoju oloko
Iba l'awọn
Ọlọta ma a la a re
Ko ma dogba
Ọkan ko gbodọ
Ju ọkan L'Ọffa
Ti ọkan ba
Ju ọkan
Oba mi ko won roro

X X X X X

O darinnako
O d'oju ala
O bi Kori ni
Lokere Kajọni
Ipade dọjo miran
ojo rere
Dakun Ma jokun
Ma j'ekolo
Ma ṣe K'olo
Onimọ bo dorun
Ohun ti nwọn
Ba ojẹ ni
Ko ma ba wọn je o

Fọlọrunṣọ ki Baba
Mase gbagbe
Lati ki iya wa
Abẹbi ọgọ laye
Ọmọ ibu owo
H'aburo wa

Segili la Shoyinka
Pe ipade d'ese
Jesu Krist o
Ṣunre! Sunre!! Sunre!!!

## Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

### Mo Ba Ganiyu Dawodu Yo

Olotu, Jọwọ gba mi laye ranpẹ yi ninu gbajumọ iwe Irohin Imọlẹ alaka gbadun lati ki Ọgbẹni Ganiyu Oluwa le Dawodu ku orire ti alaga Ijọba ibilẹ eko ti wọn yan si

Mo ba Ọgbẹni Dawodu yọ pupọ o ku orire bi a ba ni se ere lesọ asiwaju rere ni Dawodu ise o si to si aye ti nwọn yan si yi nitori o fi gbogbo ara ati emi rẹ sisẹ fun idagbasoke ilu Baba rẹ o si tun duro ti ẹgbẹ Afẹnifere nigba iponju ni Alaiko bikita fun ohun to le tidi rẹ jade si

Ọgbẹni Dawodu, asiko ti yio to wa lara lọmọde lagba onile ati alejo ni ilu Eko Oluwa yio si ma ṣe amọna rẹ ninu gbogbo idawọle rẹ,

Emi ni
Azeez Shittu Ebedi
EKO

### E ku orire o

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu Iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati ki awọn ti a to nube ni Ward H 1 titi de Ward H 6 fun yiyan ti nwọn yan Ọgbẹni Ganiyu Ọlawale Dawodu gẹgẹbi Alaga Ile Igbimọ Ijọba ibilẹ ilu Eko ati papa mo tun ba Alaga titun na yọ pe ki o ku orire fun ori aga ti Ijọba ibilẹ ilu Eko ti nwọn yan si gẹgẹbi Alaga

A si dupẹ pupọ fun Ọlọrun Ọba fun iṣẹ ti Ọlọrun yan si gẹgẹbi ẹni a ọkọ ti nwọn yio yan ni Ward H 2 gẹgẹbi Alaga ti Ijọba ibilẹ ilu Eko lati Ig ati nwọn ti nṣe Ijọba ibilẹ ilu Eko bọ

Adura mi nipe ki Ọlọrun jẹki igba rẹ san gbogbo awa enia Ward H 1 titi de Ward H 6 ati papa julọ awọn enia ilu Eko ki Ọlọrun Ọba jẹki Alaga titun na fi ẹmi gigba lo aye rẹ na pẹ o

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ ajinde yio ma jẹ fun nyin o

Emi ni
Azeev Shittu Ebedi
Eko

### Alagba O Di Ọwọ Nyin O

Olotu Jọwọ gba mi ni aye diẹ nino iwe rẹ ti nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati kes awọn ti o jẹ ọmọ Yoruba ki nwọn lọ ronu jinlẹ gidigidi ni asiko yi ki nwọn lọ ma fi ti awọn Ipinlẹ ta ko kọgbọn.

Bi ija ba wa larin awọn ẹgbẹ Oṣelu ni Ipinlẹ iṣe ti o yẹ ki awọn alagba Ipinlẹ aa ma se ni pe, nwọn npe wọn papọ nwọn a si da ebi fun ẹniti o jebi lati are fun ẹniti o jare nigbana ẹniti o jẹbi yio tọrọ idariji lọwọ ẹniti o jare.

Ṣugbọn ti awa Yoruba yatọ patapata nipa ọgbọn madaru oju a ma ti wa l ti da e ia nla lebi l ju rẹ nipa ṣiṣe bayi ao wa ẹma pẹ ọrọ sọ ni ipari ao sọ pe awọn mejeji ni o jare ko si bi ija na ti pari to ti ko tun ni jẹ jade mọ nitoripe lori madaru ni a gqe idejọ le.

Mo bẹ awọn alagba ti o fẹ pat edeaiyede ti o ti wa nilẹ lati bi ọdun mẹta sẹhin pe bi nwọ ba fẹ pari ija na patapata ki nwọn da ebi fun elebi ati are fun alare ki nwọn si kilọ fun awọn alaṣepo,

Emi ni
J A Ayanwole
IBADAN.




### Angelina Super — Rose
(O TI LỌ WA JU)

Eleyi ṣẹṣẹ jade ni ko si nita rara aṣẹṣẹ jade akan a ko mọ iṣiti o lọ ohun pataki ti a mọ nipe "O ti lọ wa ju"

Super rose yi wa fun ipara gbogbo enia lọmọde lagba lọkunrin ati lobinrin o tun wa fun irun didi ati kiko lowu o nmu irun ọkunrin papa ma dan ki o si jọlọ o ma fun ara ni ẹwa ak tun awọ ara yio jẹ yọ jade perepere

Bi enia dudu ba loo yio ma dan gẹgẹbi jigi enia pupa agaga ṣe lyen ti wa tẹlẹ.

Tere sare watabi ki o kọwe fun tirẹ loni ki o to tan nt "International osmetic Industries" 36' Ọmọwunmi Si jreet, lẹhin kanCu Mushin E tọju ara ati irun nyin ẹ tọ lu pẹlu awujẹsulọ nyin owo pọku ni 1/3d fun ẹyọ kan 5/- fun mejila ọmfun alaye si .

# Kere o Kere o! Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanunhanuu Egbogi ni LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ilẹ Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tọmọde t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan ọ wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo giriki ati atamatase fun "JẸDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya tabi pe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi iju, Igbẹ sise, aiko ri igbonsẹ deede, inurirun nigbakugba ara wiwo, Ẹsanri ẹhin didun sisan ati aiko riran kedere ko doro buruku ara, aisan Onigbameji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ni ki siak ti nwọn nba egbogi LEOPILLS nitoripe o tun ma tun ẹjẹ ṣe enia nipa sisọdi ọtun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU.

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla sile mẹfa abọ (6/-6 pere Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere. Bere Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A nta ti e ba fẹ ni Ṣọbu awọn:—

ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street,Yaba

# Balogun Kesi Awọn Ọmọ Ilẹ Igbomina

Igbomina:- Ọgbẹni J. K. Balogun ti o tun jẹ alaga ẹgb ọdọ Afẹnfẹre ni o tu ran awọn ọmọ Igbomina ieti leri irọ apitunpa ti ẹgbẹ Olomi (NPC) maa pa nigba gbogbo fun awọn enia ti wọn ni Igbomina bi ibo didi nati sunmọ etil eyiti o mu inu awọn enia dun sugban bi nwọn bati dibo fun ẹgbẹ Olomi tan nwọn ko ni mu ọkankan ṣẹ ninu ileri nwọn na o wa tua nrọ awọn enia ilẹ an ki wọn yara ko eti ikun si irọ ti nwọn yio tun pa laipẹ yi ni tor pe ibo Ipinlẹ Ariwa yio waiye ni ọdun ti nbọ

Eyi ni ọrọ ti ọgbẹni J. K. Balogun sọ "Akoko to fun ọmọ ilẹ Igbomina ti o wa ni le ati l ko ki nwọn ronu jin lẹ dada lori irọ ti ẹgbẹ Olomi (N P C) maa pa fun ilẹ Igbomina bi ibo ba sunmọ etile ninu irọ wọn ni wọnyi.

Ekini:- Ẹgbẹ Olomi nilẹ Igbomina yio ni Ipinle Division ti ẹ lati ọdun 1964

Ekeji:- Ẹgbẹ Olomi nilẹ Igbomina yio ni Olopa ibilẹ tirẹ

Ẹkẹta: Ẹgbẹ Olomi sọ pe ilẹ Igbomina yio ni ile Oogun

Ẹkẹrin: Ẹgbẹ Olomi tun sọ wipe ọda yio wa ni awọn oju ọna to wa ni Igbomina paapa ilu Igbaja Oke Ọdẹ Isin ati bẹbẹ lọ pẹlu irọ omi ra

Ẹkarun: Ẹgbẹ Olomi tun ni awọn ọna ile wa yio wa ninu ile Igbomina awọn Ọba loba ni ilu Kadana titi o fi di asiko ti mo nkọ iwe yi a lọ ni a ri a ko ri abọ mọ ra

Mo wa tun bi enyin ọmọ Igbomina eewo ni a wa ri ni nu ẹ o? A fi ki oko ori ki o maa le ..l ni odọdun ni ilu ko kan mo tun bi nyi lere njẹ a ri iṣẹ se ni ilẹ Igbomina bi? Akoko to lati kọ ẹgbẹ Olomi sile patapata ni tor pe orisa ti ko ba gbeni ko yẹ ki a fi owo rago.

Ni Ọdun ti nbọ ni ao tun dibo sile Igbimọ Asofin tilẹ Ariwa Nigiria awọn ẹgbẹ Olomi (NPC) yio tun gbe iro nwọn de mo ba enyin ọmọ ilẹ Igbomina pe asiko to to ti o yẹ ki a kọ ẹgbẹ Olomi pẹlu irọ ti ko ti nwọn lo ju ti nwọn npa fun wa

Ẹjẹki akọ ẹgbẹ wọn ninu ibo ti nbọ yi igan ti won nmu wa yi to ẹgẹ Yoruba ni t a ba ntiju fun wọn e re ni nwọn npe ni nitori idi eyi ẹjẹki a fihan wọ pe awa ki ise ago a mọ oh n ti a nse

Nwọn mo ọ a ti nwọn maa fi dẹ mẹkunnu ninu lati dibo fun ẹgbẹ won ni agbara ẹnyin ọmọ Igbomina ẹ jẹki ajijọ kọ ẹgbẹ yi ni Ipinle wa nitoripe nigbati a o dibo fun won won ko se wa ni oore kankan nigbati a tun dibo fun wọn tan ni gbana ki ẹgbẹ Olomi wa gbagbe ilẹ wa patapata ki anfani obi orogbo nigbati a pa ko awa tun bujẹ o k r a sita Sango gba bi ọrọ awọn ẹgbẹ Olomi ti ri ni ilẹ wa niyi.

Lẹkan si mo tun kesi gbogbo ẹnyin asoju ẹgbẹ yi ni ile Igbimọ Asofin ti Ipinle Ariwa ki wọn sofun awa ọmọ Igbomina pe kosi ore kankan ti ijọba Ipinle Ariwa se fun wa lati ọdun 1951 a fi iro pẹlu lile ti owo ori wa nle sii ẹ jọwọ ẹyin ọmọ Igbomina ẹjẹki asan ki a rori wa wọ ki a ṣi ji ki a woye ẹ jẹki nwọn a darapọ mọ ẹgbẹ Amuludun ẹgbẹ Afẹnifẹre ti ilẹ Igbomina ki nwon le gba wa lọwọ awon aturọta bi club ẹgbẹ olomi

Labara Ọlọrun ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre ni yio ko gbogbo aye ijoko ti o wa ni ilẹ Igbomina ninu ibo ti nbo yi

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ireti si mbe fun ọ aya fi ki o lọ gbogbo ọsẹ na pẹlu awọn ọrẹ timtimọ rẹ ki o si ṣe ohun ti o wa ni ọkan rẹ lati ṣe.

PISCES (21 Mar 20) Alafia ara ko ni si fun ọ lon niror na eyi ko ni jẹki ara rẹ ya si iya iṣẹ ṣiṣẹ ṣugbọn ibi o ba le gbidanwo ti o si ṣiṣẹ alafia yio de si ọ.

ARIES (Mar 21 April 20) Ọpọlọpọ ire yio de si ọ ọsẹ yi tobẹ ti iwọ yio lo gbogbo ọsẹ yi gbadura larin awọn to fẹran rẹ iwọ si ṣe orire.

TAURUS (April 21 May 20) O yẹ ki o ma lo ọgbọn yri re ninu ohunkohun ti o ba nṣe nitori enikan wa ti o ma ṣe ilara rẹ ti yio si ma jowu rẹ ki o ṣe pẹlẹ lọdọ luwarẹ

GEMINI (May 21 June 21) Ọpọlọpọ awon enia yio opobirikoto yi ọ ka loni ni ori ki o ma kiyesi ara nipa iru ileri ti iwọ yio ma ṣe fun enia.

CANCER (June 22 July 22) Egbogi kan ti iwọ to yio dara fun ọ ni lilo ki o si furamọ awọn ti o ba ri wipe nwọn jẹ rere si ọ

LEO (July 23 Aug 23) Iwọ yio ri itẹlọrun lọ a kọna ti u oa gba loni, ohun kan ti o ngbero lati ṣe yio bọ si ṣiṣe, sugbọn maṣe jẹki igberaga rẹ papọju.

VIRGO (Aug 23 Sep. 23) Gẹgẹbi o ti ṣe l na tun ọrọ na ro, jijẹ pẹlu suga, nigbati ni ire rẹ yio jẹ tirẹ

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Ma ọkan kuro nibi amodi ti o tun nṣe royiroyi re Iwọ yio jẹgbadun larin awọn ọre rẹ loni sugbọn ki o ma gẹgẹbi iwọ yio ti ṣe na owo

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Gbogbo iṣẹ wọ ntun lo mbọ ọ yọ ayọ lati mu ohun ti o ro lọkan rẹ ṣẹ kiki wipe ki o se ol ati ol dodo

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ayipada titun yio fi ara han ni iwaju re ki o ma e s royiroyi kan

CAPRICORN (Dec 22 Jan 31) Maye se a ọ ọkan i ipa ti o afẹ ti o m ṣe jẹki awọn ti ọgọ ni ai are canda ọ sinu iauwo rẹpẹtẹ kan.


## EGBOGI JEDIJEDI

BERE FUN EGBOGI

### "CYCLEVEN"

Arun Jedijedi jẹ okan ninu amodi ti o buru ni patak fun Ọkunrin ti o si lagbara lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti wọn a ma polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la le ri mẹwa ninu ogọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara. Awọn elomiran lere wipe boya bi awọn ba lọ si ile Dokita lati lo ke eyiti o ba nyo jade lati omusu ku ni pa bẹ awon o bo lowo rẹ palapata

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara: Lẹnin odun uie lyonu rẹ yio si tan ma bẹrẹ bakanna, Orisirisi Jedijedi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbonse dede tabi lojojumo elomiran nipa ijoko ni ojukanna selu lojojumọ tabi gigun keke ylogere (Basikulu) pupo elomiran ewo nipa ijẹ Ṣuga tabi onirurú ohun adidun pupo ju. Jedijedi orişirişi ni o wa ewo ni tirẹ? Bi o ba nyo jade ninu olusu tabi ti o ba nmu wa lẹhin igbonsẹ tabi ba nyo ti o ba ṣe igbonsẹ tan ni, tabi ti nrin o ninu omusu ni eyikeyi ti o bara bere egboki "CYCLOVEN" ti awon Oyinbo Jamani fere wa idi rẹ ko ki o si danwo o iṣi meta ni o da u wipe iwo yio bo lowo Je i p tapata alafia yio de si ekeji re ko si ninu gbogbo egbogi sa igboro ilu Nsir a Bere re ni:—

Waterloo Medicine Store
P 1a Church Street Lagos
Phone 252378 Nigeria, (Ọja Ita Faji
LAGOS

LAGOS ISLAND CHEMIST
Victoria Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

# Abẹokuta Fẹ Dabi Ilu Eko

ABẸOKUTA:- Ijọba Ibilẹ Amuṣbalẹgbẹ Abẹokuta ti ṣe eto nla kan ti yio sọ ilu Abeokuta dabi ilu Eko lori awọn nkan meremere ti nwọn fẹ ṣe sinu ilu Abẹokuta eyiti ko ni si iyatọ larin Abeokuta ati Eko ati paapa awọn nlanla ti o tun dara ni ilẹ Nuijiria.

Ninu ọrọ ti alaga Igbimọ Anugbilẹgbẹ Ijọba Ibile ni Oloyẹ J A OAkan de, ti ṣe alaye pe o je ohun ti awọn nto lọkan lati sọ ilu Abeokuta di ilu ti yio gbajumọ ti yio tun ni awọn nkankan meremere gegebi awọn miran,

O tun so pe Igbimọ on yio kọ Ibiti awọn moto yio ti maa gba ero eyiti yio ba ede oni mu pẹlu ile iyagbẹ ni yio maa lo omi bi ti Eko Igbimo na yio tun wa ọkọ ọja kan ti yio maa ra awọn igbe ati ọko nla yio tun ma ko ẹran malu niti nwọn gbe nipa wa si igboro lati tu eleyi yio din ewu ti awọn awọn mọlu ti nwọn da lanin igbon ku pẹlu.

Ise nla ti awon yio tun ṣe ni pe awọn yio tun awon ina maramana ti o wa ni igboro Abẹokuta ṣe ti awọn ina na yio fi mọlẹ rekete awọn yio tun ẹrọ ina mamamana ṣe ti yio fi ni agbara lati ṣe ṣe lo fun orisirisi awọn ẹrọ ti nlo ina.


## Iwo Ha Nfẹ Ile LEko Bi?

| | |
|---|---|
| Room | £3 |
| Room | £4 |
| Room | £5 |
| Room / Parlour | £6 |
| Room / Shop | £15 |
| Flat (Lgos) | £20 |
| Flat (EB) | £25 |

Ti o ba nfẹ okan ninu awọn ile wọnyi yara tete lo r Ọgbẹni ODUS:— 187 Bamgboṣe Street Lagos ni

deede agogo mẹrin irolẹ si agogo mẹfa irọlẹ. ijafara lewu anfani nla kan ni eyi jẹ fun ọ pe o ri ile l'Eko

## Ha Kini eleyi O




OGUN A PA YANMU — YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ An O dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun re si da ra pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ Bakanna ni o si tu yara pa ayan ati idun

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three Elephant Brand coils tirẹ loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi o ti ṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu o ri erin mẹta yi ni nwọn mu un ọ

Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu ti ile itaja kakiri Orilẹ ede yi

DISTRIBUTORS
AMOS GBENLE & BROTHERS
34, Decemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street, West
LAGOS

# GBANJO!

NOVEMEBER 15th — DCEMBER 15th 1965



Iwe itumo Ala, Etutu Sise i e wiwo, Ojo ibi Omo, ati Ogun Ajebidan 3s 6d di 1s 6d

Iwe Afose Isedale Yoruba ati Psalmu Ajebidan, 3s 6d di 2s

Turari 2s 6d Pakẹti di 1/-

le ri iwe wọnyi ra lọdọ :-
SHOYINKA ni 9, Iyalla Street, Mushin.

J. O. SHOYINKA P. O. Box 159 Mushin.

